AKIYESI

E sare tete wa ra awon oja ti o ya nile wony:-
Cash and Rent Recipt 6s dozen, £2 15s gross, Calendar 1958, 4s 6d dozen, £2 8s gross, Gbedegbeyo Hausa £1 4s dozen, £12 8s gross, Goldsmith Receipt, complete set 17s 6d, ati orisirisi oja be.
nte Iwe fun Sosi, Ile-Iwe Egbe ati bebe, ao te kiakia, yio si te yin lorun. E kowe si:- Manager

*Iyeru Press and Bookshop 68 Clifford Street, Ebute-Metta*

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma ka Iwe Irohin Imole nigbagbogbo nitoripe itan aladun mete kan yio bere nnu re laipe yi. Ekini ni itan Kogbon ninu eyi, orire omo nbe lowo iya re (apakini) itan igbesi aiye awon ayaba ati awon ologbon aiye (apakeji) itan igbesi aiye awon ore meji oni-ibiti Eko ati Olosa Ilorin (apaketa)

VOL. I No. 31. WEDNESDAY 29. JANUARY — FEBUARY. 4, 1958 KOBO KAN

# Omo Ile-Eko Meji Lodi Si Ofin

Awon yoruba moni-moni lo npa owe bayi wipe, nigbati ara ile eni ba nje Kokoro buruku ti a ko si tete wifun, bi o ba dele tan, here-huru re ko ni je ki a sun loru.

Kini e ti ro pe yio ri nigbati awon omo ile-eko nti igba kekere won fi oro ewon sere. Awon omo ile eko meji lo lo se asemase ti nwon lo yi iwe eri ti nwon gba ninu ile-iwe won pada. Boya ohun ti o mu se be ni wipe, ni asiko ti nwon nlo silewe, ere ni nwon fi asiko na se, nipa be, iwe eri ti nwon fun ko to yoju re sode, nipa be, nwon lo te iwe eri aiyederu, owo Ijoba si te won.

Oruko awon omo mejeji na ni Jonathan Idialu, omo odun marundinlogoji o kowe ni Dennis Memorial Grammar School ni Onitsha. Enikeji Nwagba, ti o tile ti nse ise ni P & T a gbo pe, nigbati awon olopa se ofin toto nipa iwe eri re, nwon ri oye pe, nse lo se jibiti nipa iwe eri na.

Nitorina enyin omo ile iwe, esin iwaju ni ti ehin nwo sare, eyiyi na to ogbon ati eko fun nyin, e je ki owo nyin mo ninu ohunkohun ti e ba nse, nitori otito lo pe.

E MA KA IROHIN IMOLE NIGBAGBOGBO

## Dr. Azikiwe Di Alaini Iya

**Onistha**

Gbuke ni a gbo irohin wipe, Iyafin Rachael Chinwe Azikiwe, eniti o nse iya ti obi Dok ta Azikiwe Premier agbegbe ile awon Ibo ni apa Ila-orun salaisi nigbati o dagba di eni odun marun-di-logorun.



Dr. Nnamdi Azikiwe

Ologbe yi fi oko re ti a pe ni Ogbuefu Obedi don Chuku-emeka Azikiwe sile ati aburo re okunrin ti o nje Ogbuefu Agbaduno ti Ogbunike ati omo re obinrin ti o nje Cecilia Arinze, ati Dokita Azikiwe.

Nwanonaku ni oruko oye ti nwonfi iya ti o ku yi je, ni odun 1902 lo wo ile oko ti nwon gbe niyawo fun Ogbuefu Azikiwe, ni aseko ti o mbe lenu ise soja ni Zungeru, ibe na lo si bi Dokita Azikiwe si.

Baba ti o bi ologbe yi je ijoye kan ni ile Onistha ti nwon npe ni Oloye Agbaduna Ozi, o si je iran oba Onistha.

Iya ka rele, ori oye yi tode o. Iya mase je okun, mase je kolo, ohun ti nwon nje ni aju e orun ni ki o ma ba won je-

## AWON OJA ODUN TITUN

Turari fun Arisiki lati ile India 10/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojise nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumeta ti a tumo si Yoruba 10/6d
Odu merindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Osu Awe 5/6d
Iwe Egbogi Ajebidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbeyo Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumo ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isegun Aje ati aiye 17/6d pelu Turari lofe
Turari Itaja 10/6d
Turari Eyonu Aje 10/6d
Abela Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ati Stamp 1/- ranse fun gbigbe oja re pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Metta
Tabi:
8, Ojo Road (Oduabore) Mushin,

## Alice Wuraola di ologbe

Irohin koto afojuba ni ojo Aie ti se 16/12/57 ti Madam Alice Wuraola Ajoke, iya Lote Amoo se alaisi si owo omo re S. A. Omoyiola ti o ngbe 57, Idumagbo Avenue Lagos.

Iya yi je okan pataki ninu igboro nla ti ise Ilu Ompuo, o tun je oniwa rere, o je onisuru enia. Lojo aiye omo aburo re, owo kanna lo fi mu won. Aburo iya wa na on ni oruko re nje Madam Elizabeth Abiara. Awon iya mejeji yi, nwon feran ara won pupo depo wipe kosi eniti o le so wipe ibeji ko niwon Nwon gbo awon ara nwon pupoju. Iya wa ta soro re yi, o to nkan bi odun marun nisinyi ti nwon sese di onigbagbo, ninu esin ti C.M.S., sugbon lenu igbati nwon gba esin na, gbogbo ohun ti nwon ma nse ohun ni nwon nse dede. Adura aro ati tale ati owo itoju ijo, gbogbo re ni nwon nse, kilasi nwon ko ja, beni Sunday School gbogbo re lope.

Iya wa se are fun igba die awon omo re de lo gbe wa si Eko lati se itoju re, sugbon nipa ife Kirisiti iya na o lo to osu meji nile dokita ki olojo to de ba Reven Babalola, on y se isin ikehin

( Wo oju ewe kerin )

